# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kejidinlogbon: Osu keje Ojo kewa, 2016**

**Akori Oro: Itelorun** - Apa kini

**Eko kika: 1 Timoteu 6: 1-6**

## Afihan

Itelorun je okan lara iwa ti o daraju ninu esin kristiani atipe enikeni ti ko ba ni iwa yi ko le wu Oluwa. Iru awon enia be gbodo tete se atunse ki o to pe ju ki won maba padanu Ijoba Olorun.
Esu mo wipe akoko kukuru ni On ni, idi re ti o fi nlo aini-itelorun lati ba aiye awon enia je, ti o si nso igbagbo won di yepere niwaju Oluwa.

- Nigbati awon odomode ko ba ni itelorun, won yio ma wu awon iwa ti ko fi ogo fun Olorun, eyiti yio fi oruko awon ebi won yi erupe, ti yio si fi awon obi won se esin tabi dojuti won ni gbangba.
- Ti o ba je wipe obinrin ni o ni iwa aini-itelorun, Iru won ki ni igbeyawo-pipe, toripe won koni le gbe ile-oko, won yio ma paro oko bi eniti nparo aso.
- Nigbati awon okunrin ko ba ni itelorun, won yio ma wu iwa-buburu ati iwa-arufin eyiti o le ba ojo-iwaju won je, ti o si le ran won ni ogba-ewon.

Awon alaini-itelorun enia je eda ti ki duro-giri, iru awon enia be ki pe lenu-ise; nse ni won yio ma si-kiri lati ibi ise kan de ekeji. Ni kukuru iru awon enia be ki ni isinmi titi di ojo-iku won.

## Awon igbese igbagbo

**Aini imo Olorun:** Bibeli so wipe, "A ke awon enia mi kuro nitori aini imo…" **Hosea 4: 6**. Ibasepe won ni ogbon ati imo, oye iba ye won wipe **ohun ti won nilo ni adura**. Won ni lati gbadura si Olorun ki o fun won ni emi itelorun, ki o si fi **anu te won lorun ni kutukutu aiye won**. Won ni lati gbadura si Oluwa ki o fun won ni ire ti okan won nfe, ti o si to si won gegebi omo Olorun **Orin Dafidi 90: 14.**
Ti awa eda-enia ba le ronu jinle, ao mo wipe adura ni ona-abayo kise aini-itelorun. A ni lati gbadura si Olorun ki o fun wa ni awon ohun ti okan wa npohungbe fun, ki o si fi awon ohun ti a nilo te wa lorun ni kutukutu aiye wa; ni ona ti yio pa aini-itelorun re patapata kuro ninu aiye wa.

**Alafia san ju ola aini-itelorun lo:** Enikeni ti o ba ni alafia-Oluwa ati itelorun, o ni ohun gbogbo, nitorina, "okele gbigbe, ti on ti alafia, o san ju ile ti o kun fun ola ati aini-itelorun ti kosi si alafia" **Owe 17: 1**.
Ti o ba je eniti o moye, iwo yio mo wipe ti o ba njeun re ni alafia pelu itelorun, o san ju owo repete ni ile-ifowopamosi ati awon ohun alumoni, laisi ifokanbale.

**Ma se ilara awon onise-ibi:** Mase jowu awon onise-ibi ti won ngberu, ti won si ngbile ninu ola nipase iwa-ibi won; sugbon ni itelorun pelu ohun ti Oluwa ti se fun o. Bi o tile kere si ohun ti o nreti, ni itelorun, ki o si gbadura si Olorun fun afikun-ire. Ni iwon igbati awon onise-ibi pelu awon oro ti won kojo ki yio pe, ao ke won lule laipe bi koriko, nwon o si ro bi eweko tutu **Orin Dafidi 37: 1-2.**
Ti o ba fe duro pe titi lailai, je ki awon ohun ti Oluwa se fun o, te o lorun, fi emi-imore han ninu awon adura re, ki o to bere awon ohun ti o fe.

**Ma se ko iwa awon keferi:** Bibeli se ikilo, wipe ki a mase ko iwa awon keferi, ki ami orun ma ba damu wa. Nitorina, o yeki a mo iyato larin kristiani ati keferi ninu oro, ninu iwa ati iise wa. Fun idi eyi, e mase huwa bi awon keferi, sugbon e ni itelorun lori awon ohun ti Olorun ti se fun yin **Jeremiah 10: 2**.
Olorun mo ohun ti o dara fun o, besini nigbati akoko ba to yio farahan ninu aiye re. Sora fun egbe buburu ti won le jeki o ma huwa aini-itelorun, toripe egbe buburu ba iwa rere je **1 Korinti 15: 33**.
Mase ba ajosepo ti nbe larin iwo ati eleda re je, mase jeki awon ore tabi egbe buburu ba awon iwa rere re je, nipa aini-itelorun.

## Olorun olupese wa

**Ohun gbogbo ni nwoju Olorun:** Ohun gbogbo ti Olorun da ni nwoju Re lati pese onje fun won ni akoko ti o ye. Olorun nikan ni Olupese ti O le pese onje ati ohun gbogbo ti okan wa nfe fun wa. Eyi tumo si wipe Olorun ni Eda kansoso ti nte ife gbogbo alaye-okan lorun:

- On ni eniti nte ife awon eranko ati awon kokoro lorun,
- On ni eniti npese ohun ti awon eiye ati awon igi nilo, ti o si nte ife won lorun
- Ko gbagbe lati mu ife awon eja ati awon eda ti ngbe inu okun se.
- Pataki-julo o nte ife awa eda-enia ti a da ni aworan Re lorun, awa ti o si fi joba, ti a si nse ikawo lori ohun gbogbo ti o da sinu aiye **Orin Dafidi 145: 15-16**. Ona ti o fi le ri nkan gba lowo Olorun ni ki o ni itelorun, ki o si duro

de e lati pese awon ohun ti o ku fun o.

Jesu Kristi salaye koko yi nigbati o wipe "e mase se aniyan nitori emi yin ohun ti e o je, ati fun ara yin ohun ti e o fi bora. Emi ko ha ju onje lo? tabi ara ko ha ju aso lo? E sa wo eiye oju orun; won ki ifurugbin, beni won ki kore, nwon ki si kojo sinu aba, sugbon Baba yin ti nbe ni orun nbo won.
Eyin ko ha san ju won lo? Tani ninu yin nipa aniyan sise ti o le fi igbonwo kan kun ojo aiye re? Ese ti eyin fi nse aniyan nitori aso? Kiyesi lili ti nbe ni igbe, bi won ti ndagba; nwon ki isise, beni won ki iranwu" **Matteu 6: 25-28**.
Ese bibeli yi yio wasi imuse ninu aiye wa ti a ba ni itelorun pelu awon ohun ti Olorun ti se fun wa, toripe enia alaini-itelorun ko le wu Olorun, besini ko le ba Olorun rin.

**Olorun nse dogba-ndogba:** Opolopo enia ni won ma nfi were pe Olorun lejo nitori ipo ti won wa, awon miran a ma bere ibere omugo lowo Oluwa tabi ki won ma lo Olorun nifun, nigbati awon kan nsiyemeji, ti won si nse atunwi asan; nitori ipo-kotemilorun ti won wa.
Ni tooto awon enia ti won ma nlero wipe Olorun ko se ohun dogba-ndogba fun won ni lati pa ero buburu yi re ninu okan won, ki won si ni itelorun; ki won ba le ri ire ti aiye won nilo gba lowo Oluwa. E jeki o ye wa dajudaju wipe, Olorun nse dogba-ndogba si gbogbo eda ti O da, O je olotito ni gbogbo ona Re; nitoripe On ni Onidajo gbogbo awon onidajo, besini On ni Onidajo gbogbo aiye.
Nitoripe oye ko ye awa eda-enia, tori re ni awon enia se ma nwipe Oluwa kose dogba-ndogba; niwon igbati bibeli papa jeri wipe ona Oluwa gun sugbon ona awa eda-enia ni ko gun **Esekieli 18: 25, 29, 33: 17**.
Awon enia ma nse asise yi, nitori Olorun ki ri nkan bi enia se nri tabi ki o ronu bi enia se nronu toripe "Ero Mi ki se ero yin, beni ona yin ki se ona Mi, ni Oluwa wi" **Isaiah 55: 8-9**.
Nitoripe nkan ko lo dede fun o, ko tumo si wipe Olorun ki se dogba-ndogba tabi o tumo si gafara fun o lati gbe aini-itelorun wo. Ti o ba duro de Oluwa ti o si ni iforiti, eto Oluwa ti o daraju ife okan re lo yio jeyo tabi farahan ninu aiye re nigbati akoko ba to. Ma ranti ni igbagbogbo wipe asiko Olorun ni a daraju, torina duro de akoko Re.

**Ki se nipa ipa:** Ohunkohun ti o ba nsele ninu aiye awa olufokansin, Olorun mo si isele na; o ni idi ti Olorun fi jeki o sele, besini o ni awon eko ti Olorun feki a ko ninu awon isele na. Siwaju si, kosi ohun ti enia le ri se ni aseyanju nipase aini-itelorun, sugbon opo nkan ni enia le se ni aseyege, bi enia ba ni itelorun ti o

si gba Oluwa laaye lati gba isakoso.
Jeki o wa ninu okan re wipe, ohun rere ti o ba nsele si o tabi itesiwaju ti o de ba irinajo re; ki se nipa agbara re tabi ipa re. Ki ise nipa ipa, ki ise nipa agbara, bikose nipa Emi Mi ni Oluwa wi **Sekariah 4: 6**.
Niwon igbati kosi ohun ti o le saa-jo ki o si se aseyanju lori re laisi Emi Oluwa, kiwa ni idi ti a ko fi le ni itelorun; ki a si duro de Oluwa lati so aiye wa di otun.

**Awon nkan amaiye-derun:** Bi o ba ti ni awon ohun amaiye-derun, o yeki o ni itelorun, ki o si ma gbadura si Olorun lati te o lorun lori awon nkan toku, ti o nilo ninu aiye re. O ni lati fi emi-imore han si Olorun, toripe opo enia ninu aiye loni ni ko ni awon ohun amaiye-derun ti fi owo yepere mu.
Won ko ni awon ohun amaiye-derun yi, kise nitori afowofa won, sugbon nitori isoro ti o koja ojo-ori won; bi ogun, ajakale arun ati oro-aje ti o denu ko ile **1 Timoteu 6: 7-8.**
Niwon igbati a ko mu ohun kan wa si aiye, besini a ko le mu ohunkohun jade lo, e jeki a ni itelorun bi a ba ti ni awon ohun amaiye-derun, ki a si duro de Olorun lati mu awon ife wa toku ti a nreti se.

**Kapa ifekufe re:** Sa gbogbo ipa re lati ri wipe o kapa awon ife-okan re, ki Satani ma ba dan o wo nipa aile-telorun ife-okan re. Ti o ko ba le ko ara re tabi ohun-elo re ni ijanu, Esu yio lo aini-itelorun lati tan o kuro ni iwaju Oluwa. Ranti wipe olukuluku enia ni a ndanwo, nigbati a ba ti owo ifekufe ara re fa a lo ti a si tan je, ni bibeli wi **Jakobu 1: 14-15**.
A mo wipe idanwo nwa nipase ifekufe okan wa, eyiti o si nmu ki a fa wa lo kuro ni oju-ona otito. Nitorina, kiyesara fun awon ife-buburu okan re eyiti o le bi ese; toripe ti ese ba dagba tan yio bi iku tabi ki o yori si iku.

**Die ti o ni dara:** O san ki enia ni iwa-bi-Olorun pelu ohun die, ju ki enia o je eni buburu ti o ni opolopo ola tabi oro. Bibeli fi idi re mule wipe, ohun die ti olododo ni sanju oro opolopo enia buburu **Orin Dafidi 37: 16.**
E mayo, ki e si ni itelorun lori ohun gbogbo ti e ni, toripe o daraju opolopo oro tabi ola ti awon onise-ibi kojo.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kokandinlogbon: Osu keje Ojo ketadinlogun, 2016**

**Akori Oro: Itelorun** – Apa keji

**Eko kika: 1 Timoteu 6: 1-6**

Gegebi ati so teleri wipe awon alaini-itelorun enia koni gba ohun ti Olorun se fun won, eyiti o fi ye ki won ma dupe, ki won si ma fi emi-imore han si Oluwa fun anu re lori won; ejo ni won yio ma ro pelu awawi wipe, o yeki Oluwa se ohun ti o dara jube-lo fun awon.

Opolopo kristiani ni o wa ninu ide, ti ogun si nja aiye won nitori ifekufe ati afe-aiye ti njagun ninu ago-ara won lati le gba isakoso aiye won tabi lati dari won. Awon ifekufe wonyi le je awon ohun ti a nfi oju se, o si le je nipa awon ohun ti nwo enu wa tabi eyiti a nfi gbogbo ara se **Jakobu 4: 1.**
Ifekufe-ara ati aniyan aiye ti njagun ninu awon eya-ara wa ni orisun ogun ati aini-ifokanbale ti nbe larin awon ara mi ninu Oluwa. Lati isinyi lo, e jeki a ni itelorun pelu awon ohun ti Oluwa se fun wa, ki Satani maba lo ongbe-ifekufe ti nba ago-ara wa jagun lati da aiye wa ru.

Awon enia miran larin wa, nda Olorun lejo fun ipo-kotemilorun ti won wa lowolowo, won ti gbagbe wipe Olorun ki se aburu, besini enia ko le fi buburu dan Olorun wo ni bibeli wi **Jakobu 1: 13**.
Torina, ni igbakugba ti Esu ba ndan wa wo, nitori aini-itelorun wa, e mase jeki a wipe "lati owo Olorun ni a ti ndan wa wo". A ko le fi ibi dan Olorun wo besini On na ki dan enia wo ( Satani ni oludanwo).

## Awon Eko nipa itelorun

Ao menuba ni kanmo-nkanmo awon eko nipa itelorun ti o wa ninu bibeli.

**Ni itelorun:** O ni awon ewu ti enia ti o talaka ndojuko, besini o ni awon ewu ti enia yio la koja bi o ba je olola-enia. Nigbati enia ba l'owo, igberaga le gbe wo bi ewu, ni ona ti kofi ni fi Oluwa pe tabi ki o ma ro wipe "tani Oluwa" toripe awon ohun ti on kojo nipa laala ati mimose on ni.
Besini ti ise ba se enia ni aseju tabi ti enia talaka, o le muki enia jale tabi se awon ohun ti yio t'abuku ba Oluwa ; nipa be enia a si dese si Oga-ogo. Nitorina, ohun ti o daraju ti o le se ni wipe, gbekele Oluwa ki o si fi aye sile fun lati se ohun ti o

dara fun o.
Gbadura si Oluwa ki O se o ni olooto-enia ati eniti o se fi okan-tan, beere lowo Re wipe ki o mase fun o ni osi, besini ki o mase fun o ni oro; sugbon ki O fun o ni Ire ti yio te bukata aiye re lorun. **Owe 30: 8-9**.
Ni itelorun pelu ipo ti o wa lowolowo, Ki o si beere lowo Olorun lati te o lorun pelu awon ohun ti o nilo fun aseyori irinajo-igbagbo pelu awon ohun ti iwo yio fi je enia l'aiye.

Bibeli fi idi re mule wipe "ki olukuluku enia duro ninu ipe nipa eyiti a fi pe e" **1 Korinti 7: 20.** A ni lati jeki oye alaye ese-bibeli na ye wa wipe, kise ipe nikan ni ese-bibeli yi duro fun bikose ohun gbogbo ti o ni'se pelu igbesi aiye wa ni o ntoka si. Nitorina, mase huwa lodi si ipinnu-rere ti Olorun ni fun o, nipa aini-itelorun, ki o maba ni ipa-buburu lori eto ti Oluwa ni fun aiye re.

**Imoran Johannu Oni-tebomi:** Johannu gba awon omo-ogun ni imoran ni igbati won bere lowo re wipe, kini awon le se lati wo ijoba Olorun. O so fun won wipe:

- E mase huwa Ipa tabi fi ipa gba owo lowo enikeni
- E mase s'eke tabi re enikeji je
- E jeki owo-onje tabi owo-ise yin to nyin **Luku 3: 14**

Mo gba wa ni imoran loni wipe ki a ni itelorun lori ohun gbogbo ti Oluwa se fun wa, ki se lori owo-osu wa nikan, ki a ba le jogun ijoba Olorun.

**Ebun Olorun:** Mo fe ki a mo wipe enia le ko oro-jo tabi ki o ni ola nipa aini-itelorun, sugbon eyi ko tumo si wipe yio ni agbara lati je ninu ola tabi oro na. Ebun Olorun ni bi enia ba ni alafia ati ifokanbale lati gbadun ire ati ola ti Oluwa yonda fun **Oniwasu 5: 19.**
Niwon igbati o je wipe ebun Olorun ni, ti enia ba ni agbara lati je ninu oro re ati lati mu ipin re, ati lati yo ninu laala re. O yeki enia ni itelorun lori awon ohun ti Olorun nse lowolowo ninu aiye enia, ki a si fi suru duro de e fun asepe tabi awon ti o dara jubelo.

**Ibukun ti koni ibanuje:** Ibukun Oluwa ni imu ni ila, laisi lala, bi enia ma fi ipa wa owo tabi ti o gba ona-alumokoroyi lati ni owo, papa-julo ti o ba je nipa aini-itelorun; iru awon okan be ko bo lowo ibanuje, besini won yio ge ika abamo je ni ikehin **Owe 10: 22**.

Ni itelorun, duro de Oluwa ti yio bukun fun o, ti ki yio si fi aye gba ohunkohun lati fi ibanuje tabi abamo kun ipin re.

## **Awon ileri Olorun**

**Olorun ko ni fi o sile:** Mase nife owo, ni itelorun pelu ohun ti o ni, toripe Olorun ti so wipe "Emi ko je fi o sile, beni emi ko je ko o sile". Ara ninu Oluwa e jeki iwa wa je eyiti koni oju-kokuro ninu, ki awon ohun ti a ni te wa lorun nitori ileri Oluwa yi **Heberu 13: 5**.
E mase jeki Esu so ileri-nla yi di asan ninu aiye wa nipa aini-itelorun. Nitorina, e jeki iwa ati ise wa tako ife owo ati iwa anikan-jopon, ki a si ni itelorun pelu ohun ti a ni.

**Emi gigun ati Igbala:** Olorun yio fi emi-gigun te wa lorun, yio si fi igbala Re han ninu aiye wa, bi a ba ni itelorun pelu ohun ti a ni, ti a si duro de lati se asepe awon ohun ti o ku ninu aiye wa **Orin Dafidi 91: 16**.
Niwon igbati o mo wipe Oluwa yio fi emi-gigun te o lorun, ti yio si fun o ni igbala-aiyeraye, kini idi ti o ko fi fe ni itelorun?

Lakotan, e jeki a fi Paulu aposteli se awokose, ki awa na ko bi enia ti nni itelorun ninu ohun gbogbo ati ninu ipokipo ti aba ba ara wa. E jeki a ko bi a ti nse di rire-sile ati bi a ti nse di pupo. Ninu ohunkohun ati ninu ohun gbogbo, e jeki a ko asiri ati ma je ajeyo ati lati wa ni aijeun, lati ma ni aniju ati lati se alaini **Filippi 4: 11-12**.
Ara ninu Oluwa, e ko bi enia ti se ngbe aiye pelu ohun bintin ati pelu opo-yanturu. E mo asiri bi enia kose ni se e Olorun, ni ojo jije tabi ni ojo airije, ni igba opo ati ni igba ti nkan ba lo o; ki a ba le ni itelorun ni ipokipo ti a wa.

**The Seal: 1 Timoteu 6: 6**
Iwa-bi- Olorun pelu itelorun ere nla ni.